# KINI BIBELI MIMO WI

"Enyin nwá inu iwe-mimọ́ nitori ẹnyin rò pe ninu wọn li enyin ni ìye ti kò nipẹkun; wọnyi si li awon ti njẹri mi" (Johannu 5:39).

"Ṣugbọn iwe-mimọ́ ti sé gbogbo nkan mọ́ sabẹ ẹ̀ṣẹ" (Galatia 3:22).

"Gbogbo enia li o sá ti ṣẹ̀, ti nwon si kuna ogo Ọlọrun" (Romu 3:23).

"Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Kò si ẹniti iṣe olododo, kò si ẹnikan" (Romu 3:10).

"Gbogbo wa ti ṣina kirikiri bi agutan, olukuluku wa tẹ̀le ọ̀na ara rẹ̀; Oluwa si ti mu aiṣedede wa gbogbo pade lara rẹ́" (Isaiah 53:6).

## OLUGBALA NA FUN Ọ

"Nitori o sọ́wọn ki ẹnikan ki o to kú fun olododo: ṣugbọn fun enia rere bọya ẹlomiran tilẹ le dába ati kú. Ṣugbọn Ọlọrun fi ifẹ On papa si wa hàn ni eyi pe, nigbati awa jẹ ẹlẹṣẹ, Kristi kú fun wa" (Romu 5:7, 8).

"Ṣugbọn a ṣá a li ọgbẹ nitori irekọja wa, a pa a li ara nitori aiṣedede wa; ìna alafia wa wà lara rẹ̀, ati nipa ìna rẹ̀ li a fi mu wa lara da" (Isaiah 53:5).

"Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹ̀ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun" (Johannu 3:16).

## IGBALA RẸ SI Ọ

"Nitori ore-ọfẹ li a ti fi gbà nyin là nipa igbagbọ́; ati eyini kì iṣe ti ẹnyin tikaranyin: ẹ̀bun Ọlọrun ni: kì iṣe nipa iṣẹ, ki ẹnikẹni má ba ṣogo" (Efesu 2:8, 9).

"Nitori ikú li ère ẹ̀ṣẹ; ṣugbọn ẹ̀bun ọfẹ Ọlọrun ni ìye ti kò nipẹkun, ninu Kristi Jesu Oluwa wa" (Romu 6:23).

Kò si si igbala lọdọ ẹlomiran: nitori kò si oruko miran labẹ ọrun ti a fifunni ninu enia, nipa eyiti a le fi gbà wa là" (Iṣe awọn Aposteli 4:12).

"Ẹ̀jẹ Jesu Kristi Ọmọ rẹ́ ni nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹṣẹ gbogbo" (1 Johannu 1:7).

## KINI OHUN TO GBỌDỌ ṢE KATO GBA Ọ LA

"Gbà Jesu Kristi Oluwa gbọ́, a o si gbà ọ là, iwọ ati awọn ará ile ré pẹlu" (Iṣe awọn Aposteli 16:31).

"Lōtọ, lōtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba gbọ́ ọ̀rọ mi, ti o ba si gbà ẹniti o rán mi gbó, o ni iye ti kò nipẹkun, on kì yio si wá si idajọ; ṣugbọn o ti ré ikú kọja bọ si ìye" (Johannu 5:24).

**Word Of Truth**, P.O. Box 1126, Kaduna, Nigeria